ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL X V NO 915 LAGOS SATURDAY APRIL 11 - APRIL 17 1964 K BO

EYI ARA!

# Adajo Marun Lo Nse Ejo Awolowo

## Olopa Po Jara

ERO – Ogunlọgọ awọn Ọlọpa-ode ati Ọlọpaau nį Ijọba ko lọ sį gbangba Kotu-ganran ni owurọ ana nį Ọdan ki nwọn to bẹrẹsį ro ẹjọ kotẹmilọrun tį Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olorį awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnįfẹre (A G) pe ori ẹwọn ọdun mẹwa ti Adajọ George Showẹmimọ sọ ọ sį pẹlu awọn mẹrindįnlogun miran.

Irọkẹkẹ ti awọn ọlọpa na pẹlu awọn jọgi wọn pọ pupọ ju ti o fi jẹ wipe ninu ogunlọgọ awọn enia pataki pataki ti nwọn wa lati ilu bi Abẹokuta, Ibadan Ijẹbu-Ode, Shagamu, Ilaro, Ekiti Coutonu, Ajaṣẹ ati awọn ilu bẹẹbẹ ti wa lati gbọ ọrọ ẹjọ na ko raye wọle, awọn enia diẹ ni awọn ọlọpa g a laye lati wọle, gbogbo awọn ti nwọn wọle na ni nwọn yẹ nkan ti o wa lara wọn wo kinnikinni nwọn ko si rį nkan jamba lọwọ ẹn kẹni rara.



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

Awọn ogunagbongba adajọ-agba marun (meji jẹ alawọ-funfun ninu wọn) ni nwọn joko lati gbọ ẹjọ ko-tẹ-mį-lọrun na nį ana awọn adajọ na ni Ọlọla Adetokunbọ Ademọla, Ọlọla Louis Mbanefo (olori awọn adajọ Ila Orun), Ọlọla Lionel Brett, Ọlọla Vahe Bairamin ati Adajọ John Idowu Conrad Taylor.

Lọya Oyinbo meji ti iwe ofin nke lori wọn pẹlu awọn lọya enia-dudu mejį na nwọn dide fun Oloye Awolọwọ latį fi ọna mẹrįnlelogun han awọn adajọ wįpe Adajọ Showẹmimọ kuna lati sọ Awolọwọ sẹwọn; orukọ awọn lọya mẹrẹrįn na ni Victor Durand pẹlu ekejį rẹ Thomas Kellock ati Ọgbẹni M.A Ọdesanya pẹlu Ọgbẹni Olu Ayọla lati Ibadan.

(W yoku loju ewe kẹjọ)

### Awon Ibo Pade Agbako Lodo Hausa

ZARIA — Eyi ko tofo fila Imale ku pẹrẹku ni awọran gba-ko-fi-sọgbọn kan ti o jade nįnu įwe ọsọsẹ ti awọn Hausa tį nwọn npe ni Gaskįa Ta Fi Kwabo ti nwọn ya ọgbẹni Fulani oni malu kan ti o nda awọn malu rẹ lọ jẹ koriko ni papa,

Ọrọ akọle ti nwọn kọ le aworan na fa ọrọ alufasa lọwọ pupọ, nwọn ni awọn Hausa ni awọn nį oke Ọya Ọlọrun ni o sį fun awọn n nwọn malu ki awọn ma jẹ wọn awọn ko ni ko wọn wa si isalẹ lọdọ awọn ajẹnia mọ.

Nwọn ni nwọn kuku pọ bi esu ni įlu awọn Ibo, įyẹn na to ki nwọn ma pa ara wọn jẹ.

### Awon Omo Ilewe Ilesha Bere Ise

ILESHA — Gbogbo ẹsọ awọn akẹkọ ilewe giga Ilesha nį nwọn pe perepere sį įlewe na ni owurọ ana lati ma ba iṣẹ wọn lọ, a fi awọn melo kan ti awọn janduku kan palara ti nwọ w ni ile iwosan awọn Wesley Guild n nwọn ko le ba wọn bẹrẹ ilewe na ti nwọn paṣẹ wipe awọn sį ni ana.

Ni irọlẹ įjẹjẹ ni agan bẹ silẹ ni Ilesha nigbati Oloye S L Akintọla pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ wolu lati lọ da ẹgbẹ wọn tuntun silẹ nwọn nwọn ni awọn kan nlọgun ole ! ole! ole le wọn ori bi awọn tį nfoju kan wọn.

A gbọ wįpe awọn ki tun bẹrẹsi s ... wọn eyi n ... mu ... awọn alamojuto ... Iwọ orun paṣẹ lati Ibadan wipe ki nwọn le awọn ọmọ ilewe na kuro ninu ilewe ki nwọn si tun da Olorį ilewe na, Alufa J. Akinyẹmi ti o nkọ lẹkọ duro lẹnu iṣẹ.

A ko mọ bi nwọn ti tun ro ọrọ awọn ọmọ akẹkọ na si kį nwọn to tun paṣẹ wipe ki nwọn pada si ile iwe ... aka.

**Ka oro Iyawo Oba ti o ji omo gbe ni ewe oju Kefa iwe yi**

# Baba Olowo Ele Wewon L'Eko

EKO... Adajọ kotu awọn Ọlọpa sọ baba Ọlowo-ele kan, Saka Oshina ke ati ekeji rẹ, Victor Bello sẹwọn ọdun mẹsan mẹsan fun iwe owo-ile kan ti awọn yi pada lati bi ọdun mẹrin sẹhin.

Awọn ọlọpa ni obinrin kan ti awọn npe ni Comfort Williams lọ ya pọnun mẹdọgbọn nigba kan lọdọ baba Olowo ele yi, nigbati arufin Olowo ele na ṣe adehun, o yi i si igba o le marundilọgbọn pọnun (£225).

Comfort ti o lọ ya owo yi san owo titi ko tan, o ni pọnun mẹdọgbọn ni on ya tabi kiloṣe ti'owo na ko ti tan lati ọjọ yi.

Nigbati awọn ọtẹlẹmuyẹn tẹsẹ bọ ọrọ na lawọn ri wipe baba Olowo ele ni o yi iwe owo na pada; Adajọ ti o ṣe ẹjọ na ni on yio fi eleyi kọ awọn mejeji lọgbọn nitoripe iru iwa buruku bayi pọ lọdọ awọn Olowo ele.

## Britains Purchases From Nigeria

LONDON— Britain's purchases from Nigeria this year are already runing at £1 million more then last year while the month of February alone shows an increase of £750,000.

Figures just published by the Board of Trade in London show the Britain has been buying more of ymas Nigerian products, including fruit and vegetables coffee and cocoa, oilcake and vegetable oils, hides and skins timber and veneeres and palmnuts

The total value in the first two months of the year has risen from £11, 800,279 to £12,732,573. The February figures are up from £5,062,091 to £5, 742,195.

# Nigerian To Lead London Course

LONDON ... A Nigerian, now in Britain studying industrial training, has been appointed as first leader of the group of seven overseas personnel officers who are taking a month-long course, which began this week in London.

He is Mr. P O Ume-Ezeoke, Controller of Staff Training of the Nigeria Broadcasting Corporation, in Lagos.

Another Nigerian taking the course, organised by the Industrial Welfare Society, is Mr. J D Gonmwalk, Personnel Manager of Kaduna Textiles Limited.

Among other tasks as group leader, Mr. Ume-Ezeoke will lead discussios during visits made by the officers to companies and other institutions as part of the course, and aid the IWS in administration of the training programme. He will remain leader for one week.





PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of sidings) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns, all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 200 and more stations.

And what's more : you are dealing with people you can trust.

SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL






# Awon Olopa Ni "Sango" Lo Da Ijan gbon Sile Ni Ilesha

ILESHA — Gbogbo awọn ọlọpa idagiri ni nw n k... kotu awọn Ọlọpa ni Ilesha nị wurọ ijarun nig... ...wọn bẹrẹsị ro ẹjọ janduku 'ti awọn ọlẹ-...tẹ e-alufa, awọn Raimi Ajadi (ti adape orukọ re njẹ Ṣ...g... Adelabu) pẹlu igba keji rẹ njẹ Ganiye Iya...d... ati awọn mẹdogun miran ti awọn ọlọpa ni awọn ... nkan jamba lọwọ wọn.

Ọga ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ David Iyare ni o kọ rojọ, o ni on ni on ko awọn Ọlọpa idagiri lọ si Ilesha lọjọ ti awọn 'Ṣango' pẹlu awọn janduku enia rẹ da ijagbore silẹ.

Iyare ni ibi tesau moto Armelṣ ni awọn duro si pẹlu awọn ọlọpa ti on ko lọ. O ni ko pẹ ti awọn de ibẹ nị awọn ri ti Oloye Akintọla pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ mba; o nị ninu awọn ti o tẹle e lẹhin ni Raimị Sango ati Ganiyu, o ni awọn mejeji yi nwọn kọ bọ sịlẹ ninu mọto nigbatị nwọn ngbọ ti awọn enia nlọgun 'Awo, Awo Awo ati Sịki Sịkị Sịki (Zeẹk)";

Ọga Ọlọpa na ni gbara tị Sango tị bọ silẹ ni o tı bẹrẹsi rọ ojo oko si gbogbo awọn enia ti nwọn duro latị wọ mọto lọ sị id lẹ nịle moto lọ si idalẹ moto Armel na. O ni bi 'Sango' ti njoko nị o nfi ada ti o mu lọwọ ti o si ki fere mọle fti o ni ki awọn yoku tị o wa yoku ti o wa ninu moto jade.

Gbogbo wọn si tu jade nwọn bẹrẹsi le awọn enia kakirị: nwọn 'e a...ọn enia titi wọ ẹgba ...e iwe giga tị nwọn npe ni Ilesha Grammar School.

Ọlọpa yi ni nwọn lu obinrin kan ti orukọ rẹ njẹ R...seline David pẹlu ọmọ rẹ ti nwọn fẹ wọ mọto ni alubolẹ, ọga ọlọpa yi nigbana nị wọn na wa bẹ lu wọn, ti awọn si m... wa bẹ lu wọn, tị awọn sị mu ọga awọn janduku na...

Gbogbo awọn enia ... nwọn wa gbọ ọrọ ẹjọ ... na nị nwọn tu jade ... Kotu nigbati awọn ọlọ... bẹrẹsi ru aake, ada, ... akaraba, igbadị atị ... ṣi ogun tị nwọn ... moto awọn ji du...u ... jade si iwaju adajọ.

Ki nwọn to sun ẹjọ ... si iwaju, ẹnị meji ni awọ... ọlọpa sọ wipe awọn ... fẹ ki nwọn gba iduro wọ... nitoripe nwọn tun le da ijangbọn silẹ ... Ọtunla ọjọ Aje (Monda...) nị nwọn sun ọjọ gbẹjọ ... si. Awọn ọlọpa ni ọpọlọpọ awọn ọd...ran ... na nwọn tun ni ẹjọ miran lat... jẹ ni Akurẹ nibiti nwọn gbe ti ba wọn ni nkan jẹ ti nwọ ko aṣọ awọn al ṣọ.

# Faaji Ariya Nilu Eko



Eni-O...a Omo'ba M... ...n Tokunboh ni a n... nwon nfi ese p... nu ile Egbe Island ...

Eyi ni asike ti ...lola S... ilu awon Senega...

---

# Eleti-Ofe Daraba

E...ka
oro ...
loju ewe karun

# ELETI-OFE

(A NJU WON KO ŞE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME
Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XIV. NO. 916 SATURDAY April 11—April 17 1964.


## Oro Olotu :

# Ero Meka, O Digba !

Ki ogunlogo awon eru Olorun ti nlo si Meka lodun ni gunle si ebute Jeda tabi ti Kano o ye ki a fi oro keekere ki nwon pe o digba, ki a si tun se wasi fun won wipe IWA LESIN, a ko ba lo si Meka ni igba igba ti a ko ba ni iwa rere pelu gbogbo opolopo asan ni gbogbo re. Omulemofo si ni wahala ti a nlo se ni Meka ati Medina.

Enikan ninu awon okawe wa ti o pe ara re ni "OMO KEWU" ko iwe kan si wa nina, eyi ninu Eleti Ofe ose yi; OMO KEWU na ni kinni o fa a ti awon kan ninu awon Imale feran lati ma ilu Meka nigbakugba.

Ibere ola ni ibere na, oro na ko si le ye awa ogberi afi awon Alhaji ti nwon ti npora ilu na nigbagbogbo ni nwon le so nkan ti nwon nri lohun fun wa. Ilo ko jeki a mo otito pato awon enia ti awon nlo si Meka lododun.

Opolopo ni awon ti nwon nfi arugbo ara lo pelu ero wipe ti awon ba ti de ohun gbogbo iwa buruku ti awon ti hu nile ni Olorun yio dariji awon. Awon miran ni bi awon ba ti de ohun ti awon gbadura kikan kikan lori oke Arafa ni awon yio ti ma di Olowo ti gbogbo ise awon yio ti gbon danu.

Ti nwon ba ti pada de ile awon miran o wa bere wa o sise perewu. Alhaji ki puro ni a ti ngbo ri, awon Alhaji ti ode isisiyi iwa buruku ni a mba lolo won. Niteri aso pelu lati ri obinrin fe ini opoopo se nio sugbon enikeni ti o ba fe isinmi okan fun ara re ti o ba ti Meka de ki o ye iwa buruku nu nitoripe iwa lesin.

Lekan si a ki enyin ero Meka, o digba ti e ba de ki e fi iwa se apere fun awa ti a ko ti le ikì fi le mo wipe njtoto ni e ti lo si ilu mimo, iwa enyin paapa si ti di mimo.

## E ka

### Oro lori Ayaba Deji Oba Akure

(Oju ewe kefa)

# Iwe Si Olotu

# Kini Mba Won Leru?

E jowo e gba mi laye lati kansara si oro ti e fi bere lodo awon alamojuto Ijoba wa ti nwon nfi ofin olopa de wa mole nigba gbogbo wipe a ko gbodo se ipade lope, a ko gbodo wo ode lowo olowo mo lati bi odun keji.

Olotu ko ye wa si nkan ti o mba Ijoba wa leru; iyen ni wipe awon alamojuto Ijoba wa na mo wipe gbogbo nkan ti awon nse ko te awa ara ilu lorun mo? Kinni wa se ti nwon ko se tu ile igbimo ka ki a tele di ibo tuntun mi ran?

Ni adan lodo wa nihin ni igbagbogbo ni awon alamojuto Ijoba fun awon olopa lase wipe ki nwon sofin ki enikeni mase ipade lode gbangba sugbon nigbagbogbo ni awon na nru ofin na pelu awon janduku won.

Boya ofin ti o nru awon ara ilu ko mu awon alamojuto Ijoba wa ni nkan ti o nru mi leju nigbagbogbo. Sugbon a ko ri ki awon Oyinbo ma hu iwa alaito bayi nigbati a wa labe won. Bi nwon ba hu u awa na ni a o ma kowe bu won ninu iwe iroyin ti a o si ma logun won kiri.

Bi ееku-ida Oba ba wa lodo wa, o ye ki a lo o pelu iberu Olorun ki oda na ba le pe lowo wa nitoripe eniti o ni oni ko ni yio ni ola.

O oto, iwa alaise otito ati ododo nibiti o gbe ye ni o mba awon alamojuto Ijoba wa leru ti nwon fi nse onile mole.

Emi ni,
Olasupo Adigun
Oke Olukun,
Ibadan

gbogbo. Awon elomiran ni lada tabi ifonjin ese ni nwon nwa; awon elomiran ni Wayo ati lewo ni ojiji ni awon kan mba lo.

Boya a le ri awon ogunna gbongbo Alhaji ti nwon le la ona esin ti Alalaji yi fun wa nitoripe awon kan wa ti nwon ni bi enia ba ti lo sibe ko gbodo ma so gbogbo nkan ti oju re ba ri.

O dabi eni wipe nkankan wa ni ilu na ti awon ti o ba lo sibe nlo se bi awon Alawo, oro na ko ye awa ogberi.

Saago, Ebute-Metta

Emi ni
OmoKewu

## Ipara Ilu Meka

Alagba, boya e le la idi re fun wa ti opolopo awon Imale wa fi npara ilu Meka ni igba-

# Wahala Idi Bosi

E jowo e ba wa kesi awon janduku ti nwon njijadu lati wo bosi nigba gbogbo wipe ki nwon ma to sinu nin ti nwon kan sile fun awon ero.

Ki a ma puro opolopo awa ero idi bosi ni a nlun awon omo jaguda laye nigbagbogbo lati ji wa lowo.

Awon Kansilo Alamojuto eto bosi Eko ti se ona eto ti o le ro gbogbo wa lona lati wo bosi fun wa awa ni a nfe wa hala fun ara wa.

Boya awon akowe agba fun bosi le ran wa lowo lati ma so fun awon ero wipe ki awon ma to letoleto ki awon to wo bosi, eniti ko ba to ki nwon ma jeki o wo bosi rara

Emi ni
Ade Latona
Eko

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

Lati Owo Ayiluka

## Akowe Kan Gbe Edegbefa Ponun

KANO— Awon Olopa ru akowe kan Martin A. Osima ti o os se nile awon Oyinbo onisowo kan ti awon npe ni S C O A wa si iwaju adajo wipe o ji edegbefa ponun (11,000) gbe ninu banki awon Faranse, ti nwon npe ni Delafrigue.

Gegebi okan ninu awon olopanu ti nwon mu odomokunrin na, nwon ni Ogbeni kan ti o npje Fitz Silvan ni nwon ran wa gba owo-na ni eni ji ni banki na.

Nwon ni o to osu keta ki nwon to ri Silvan ti o wa gba owo na-sugbon nigbati a pon olopa se ofintoto tani ko iwe owo na ni awon olopa Kaduna ni Osima arufin yi ni.

Ni otuula ojo Aje ni nwon yio beresi ro ejo na ni nibi· Awon olopa ko ti gba iduro arakunrin na.

## Iwa Janduku Ko Ye Omo Enia

E ... ti o deran okan ninu awon ese buruku won ... ki o ... ore re, ... ki a fi agbara ba ebi ... Ija, Olo a, Ipanilara, ... ki ena gba ... lati na enikeji tabi k... o gba em... re.

Arufin ti owo ba te ti a si ... lo siwaju adajo ti a si da lebi, o ni lati jiya ese re sugbon eni ti arufin ba se ... jamba wa ninu irora, ailowo-lowo, ara riro jeki a so bi oro na tiri.

Odomokunrin kan ni adajo sa konko ewon odun mewa mo lara nitoripe o se jamba fun omode obinrin kan. Bi oro na ti lo niyi

Omobinrin na ri Odokunrin kan ti o wu lati ma ba se ore, awon mejeji si dijo lo woran ere sinima lehin iran sinima o ba okunrin na lo sile, nwon dijo jeun, okunrin na ... moto mu omobinrin lo si (Wo iyoku loju e ... e ... kejo)


E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE ti o kun fun irohin al... dun los... se.

DAGENITE BATTERIES give you a longer run for your money!




Fun ina dídá ati fun imọlẹ BP SUPERLITE KEROSINE L'ayo!




Ti o ba sepe Kerosine lo fe BP Superlite ... mbikibi, ko si wọn, o mọ daradara, ow... ju fun onje-ise, ina-titan ati lati ma f... ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo ... lọ!

# Ayaba Deji Ni Akure Jo-mo Gbe

AKURE- Iyawo Ọba Deji ni Akure ti oruko rẹ njẹ Olori Ibilọla Adesida ọni ọdun medọgbọn ni agbọ wipe adajọ-agba Ọgbẹni Fatayi Williams sọ sẹwọn ọdun kan tabi ki o fi adọjọ ponun (£150) taaran ọmọlọmọ ti obinrin na ji gbe.

Ọga Ọlọpa kan, Ọgbẹni Mgbechi Ofoegbu ro gbo-gbo ẹjọ na fun adajọ bi a ọn ọlọmọ na ṣe wa sọ fun ni tesan awọn wipe awọn ko ri ọmọ oṣu mẹ-ta ti oruko rẹ njẹ Rọpo Fabilọla ti awọn ṣẹṣẹ bi.

Ọlọpa yi ni njiru Afin Ọba Deji ni awọn ba ọkan ninu iyawo Ọba na ti o nrọ ọmọ na lọwọ on si mu obinrin lọ sọdọ Ọba. O ni ọba Deji ni ara ni nj o gbọmọ wa h n n wipe ọmọ ti on bi fun on niyi.

Olori Ibilọla iyawo Ọba na ni ki awọn ṣe on jẹjẹ. o ni awọn ai si on ri, o ni on ko mọ ghati on ji ọmọ ọlọmọ na ai atule ti a on npe Ọba, O kunlẹ o bẹ adajọ titi sugbọn ẹpa ko boro.

---

## Awon Omo Egbe Dokita Mba Ara-won Ja

EKO... Awọn ẹgbẹ Dokita Oloyinbo ti ilẹ Nigeria ti pin si meji nisisiyi lori Dokita Okechukwu Ikejiani ti awọn kan ṣẹ-ṣẹ yan na ni baba-ẹgbẹ. Awọn kan ni Ọlọla Kofo Abayomi ti o ti nṣe baba ẹgbẹ na ni awọn fẹ ki o ma ba iṣẹ rẹ lọ.

A gbọ wipe ọpọlọpọ awọn dokita atakipataki ni awọn faake kọri wipe awọn ko ni wa si ipade ti awọn pe lat yan baba-ẹgbẹ na. Tẹlẹtẹlẹ Dokita Ikejiani ni igba keji baba—ẹgbẹ na ri.

Ninu awọn doki a pata ki awọn binu bọ si ita ni bi ipade na ni Dokita oni Ake e, Dokita wol yi Dokita Flavius Akerele, Dokita J. Sh dipo ati Profesọ H. O. Thomas

Awọn ti awọn yan Ọlọla Kofo ni baba ẹgbẹ fi Dokita ọmọwe F. O. Dosekun ṣe akọwe; awọn ti Ikejiani yan Dokota F. O. Mabayọjẹ ni akọwe ti wọn.


# E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.





# Algeria Awards £25 Million Pipeline Contract To Britain

LONDON A oil pipeline connecting the Sahara oilfields with the Mediterranean coast is to be built under a £25 million contract signed by the Algerian Government and a British company, John Brown and Company. The contract covers the supply and laying of a 500 mile pipeline, with a capacity of 10,000,000 tons a year.

It will be completed within 18 months and will enable full development of the Sahara oil fields.

As part of the contract, Algerian technicians will be trained by the contractors in Britain.

A communique issued in Algiers after the signing of the contract said: "The British offer was preferred by Algeria for its general technical and financial and for the price propoed".

## Rise In Britain's Investments Over-seas

LONDON... A big rise in British investment overseas, a marked improvement in the balance of payments on current account, and an increase of 5 per cent in the "Gross National Product", are outstanding facts emerging from three official reports published in London. They set the scene for the Budget-out next week-for the financial year 1964-65.

All deal with different aspects of the economy but all bring out the rapid expansion in 1963 and the improvement in British economic prospects.

British investment overseas in 1963 increased to a net outflow of £147 million, compared with one of £89 million in 1962,



During the Opening Sesion of Federal Parliament in Lagos, the President Dr. Nnamdi Azikiwe inspected a guard of honour, in from of the house.




# Over 50 British Teachers For Nigeria

LONDON—Over fifty of the eighy British teachers who have volunteered to spend most of their long vacation in Africa, running intensive refresher courses for foreign teachers, will be going to Nigeria. And this week and next in London and Edinburgh the teachers for Nigeria-who will be working in all four Regions and in Lages—are attending special briefing meetings arranged by the British Council.

As well as learning more about Nigeria, the British teachers will study the latest methods of teaching English as a second language and see the most up-to-date developments in visual aids to teaching.

For Nigeria this will be the fourth year of these vacation courses for primary and secondary school teachers and the staff of teachers-trainin colleges.

# Hu Ha Ha Eyo De Ara Eko!



**EKO—** Irohin kan wa ni alẹana lati Iga olori awọn ẹyọ wipe awọn fẹ ṣe ẹyọ fun ologbe baba adado G, B.A. Coker ti o jalaisi ni iwọn ọdun kẹrin sẹhin A gbọ wipe ajọ kẹta ti nwọn ba ti ṣe ọdun Ileya tan ni nwọn yio ṣe ẹyọ na, iyẹn ni ọjọ Abamẹta (Satide) ọjọ mẹdogun loni.

Onirohin wa kan nfi ye wa wipe o to iwọn nkan bi oṣu mẹfa ti nwọn ti wa lẹnu ọrọ baba Coker na. Awọn kan ni nigbati ọmọloku kọ gbe ọrọ ẹyọ baba rẹ na si iwaju awọn onilu, nwọn ni nwọn kọ jale nwọn ni aya ilu ko balẹ rara. Awọn kan ni nwọn ti ibi ẹyọ ṣe awọn enia lọṣẹ.

Awọn kan ni awọn onilu ni ti nwọn ẹyọ ba le lọ irukere dipo ọpa-abata awọn ko ni lodi si wiwọde wọn rara ṣugbọn awọn baba ẹlẹyọ ni ọrọ irukẹrẹ ko si ninu eto ẹyọ rara. Nwọn ni lati ọjọ ti alaiye ti da aiye won ko gbọ wipe awọn ẹyọ lo irukere dipo ọpa-abata ri.

Eyi ti a a tun ngbọ nipa eto ẹyọ na a o ma a jẹki ẹ gbọ o lọse ti mbọ Hu Haba! mo yọ fun yin, mo yọ fara mi.

---

**AKIYESI Li agbara Oluwa a o te ARO EYO fun igbadun gbogbo eyin okawe wa ni ọsẹ ti mbọ.**

## Iwa Janduku

ile wọn Ọmọbin na fi ẹnu ko ọrẹ titun yi lẹnu, nwọn si ki ara wọn pe o di owurọ

Ṣamọṣamọ, ọdọmọkunrin kan ti o ti nṣe ọrẹ ọmọde obinrin na sare lọ sapamọ sinu okunkun o ni ki ọmọbinrin na ba on ka lọ sibi kan ọmọ na si kọ lati lọ. Bi o ti yi pada lati lọ wọ ile bẹni o fi irin Hama lu u ni agbari Fun odidi ọjọ mejila ọmọbinrin na ko mọ bi aye l'on wa tabi orun nitoripe agbari rẹ fọ. Igbameji ni Dokita ṣe ayẹwo ọpọlọ rẹ.

Nisisiyi ni biti ọrọ na di yi ọmọbinrin na ni anfani lati gba owo ina lọwọ ọd ran yi, bi o ba si jẹ wipe ninu mọto ni nkan yi ti ṣẹlẹ yio tun gba owo jamba ti mọto. Kini iwọ le ṣe bi o ba jẹ wipe iwọ ni a ṣe jamba yi si, iwọ gbogbo inawo ti o ni lati na ti amodi ko jẹ tani yio ma fun ọ ni owo jọun ninu amodi.

## Ejo Oloye Awolowo

(O tẹrẹ loju ewe kinni)

Ọgbẹni ADEDIPE agbẹjọro Ijọba ni o ko iwe tirẹ wa lati tako gbo gbo ọna ti awọn lọya Awolọwọ ba fẹ gba yọ si awọn adajọ-agba mẹtarun.

Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ paapa kọ lati wa si kotu ni ana, o ni on ko fẹ ki awọn ọlọpa ma da mu gbogbo awọn enia ti yio wa si kotu wa wo on o ni nwọn le ṣ ipa bẹ ra awọn enia pa si gbangba kotu. Awọn enia meji pere ninu gb gbo awọn ti nwọn pẹjọ kotẹmilọrun na ni nwọn le wa si kotu lana, awọn meji na ni Lateef Jakande ati J.S Lawọpin

Awọn lọya wọn sọ wabiwọsi ẹrọ lana ninu kotu ni iwaju awọn adajọ agba merun ti nwọn ngbọ ẹjọ wọn.


make it a successful
SEASON
*with* MERCEDES-BENZ
TRUCKS

MERCEDES-BENZ



**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN,
KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA,
PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Phone 23370 Editor; (Olootu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O Box 467